ADURA FUN ỌSẸ YI
Lọwọ aṣekọjọ Kasiṣe kọ ma mọ ẹni lọwọ Oluwa rere gba wa.

# IRAWỌ ★ OBOKUN

OWE ỌSẸ YI
Iakumọ ki rin ni ọsan, eni abi re ki rin oru.

Vol 4 No. 140 | ILESHA. | MONDAY. | JUNE 6 1955. | IYE OWO: TORO

## E DABO BO AWON OLUGBE ILU ILESA



ỌLỌLA OLU, KỌMOLAFẸ
Ẹnikan so lọṣẹ to kọja pe iro ni pe NCNC leri lati gẹ owori si ile meje abọ. Ṣugbọn ẹnikan tun sọ bẹ lọṣẹ yi.

## AWỌN ONITẸTẸ
(Lati ọwọ S. Lawani.)

Mo ki Olotu Irawọ Obokun e gba mi laye lati sọ ọrọ kekere yi sinu iwe eloyin momọ. Mo be Ọlọpa ati igbimọ ilu ati Kanselọ gbogbo. Ni ọjọ kejila oṣu kerin 12/4/55 ni Ọkunrin kan, nti Ibadan bọ. O fẹ lọ si Ibokun, o wa ri awọn oni tẹte ni Ikorita Idomi-esi. Wọn tan Ọkunrin na jẹ, wọn gba £9 lọwọ re wọn si fi iya jẹ wọn lu wọn ẹje sẹn u re, wọn ya ewu re perepere,

(Bere ni oju iwe 5)

## ẸNI BERE ỌRỌ LOFẸ IDI RẸ LATI GBỌ
(Lati Ọwọ John Ayọdele K. 44 Anaye St.)

Ẹ jọwọ Olotu, e gba mi ni aye lati sọ ibi ibere mi kekere yi. Mo si fe ki awọn to nka iwe Irawọ Obokun ati awọn ọmọ Obokun kọ jowọ ki wọn fun mi ni alaye lori ọrọ mi na.

Ọrọ na niyi:

Ẹ jọwọ kini Itumọ ohun ti wọn npe ni Ọfẹ?

Ohun to mu mi bere yi nipe lati nkan bi ọdun meji sẹhin ni mo ti ngbọ wipe iwe ni Ẹkọ ọfẹ, ati Iwosan ọfẹ. Lotọ a ri pe wọn kọ Ilewe kekeke kakiri, eyiti a re pe wọn bere si kọ awọn ọmọdẹ nibẹ ni ibere ọdun yi, a si ripe wọn nlọ si ile dọkita lai san owo lati nkan bi oṣu mẹta sẹhin.

Eyiti o mu mi wa wo iru iwe ti mo fi nsanwo ori, mo ri ọrọ kan ti wọn kọ sibẹ lati iwe to ti se lati bi ọdun mẹta sẹhin. Ekini ni "Education Rate" ati ekeji ni "Medical Rate".

Mo fẹ kie la nkan ti Itumọ owo yi jẹ fun mi ati Itumọ ọrọ kan ti wọn kọ si isalẹ (Flat Rate Tax Receit) wipe-(Including 10/6 Education and Heath Levy (Regional Share of Tax)"

Mo fẹ Itumọ eyi ati awọn ti o nna ati ohun ti wọn nna le lori

Iba ọrọ mi si yi o Olotu Ọwọ re koni gbe, awọn ọta rẹ koni ri o gbase lagbara Edumare Amin Ẹo tun ma ri ọwọ mi lẹhin eyi eleyi.

## IDASILẸ ẸGBẸ NCNC TI OBIRIN
(Lati Ọwọ Kanselọ S. Akindele Ojo)

Lati nkan bi oṣu kan sẹhin ni ogunlọgọ awọn Obirin Ilesa ti nwa ọna bi wọn yio tiṣe da ẹka ti Obirin ti ẹgbẹ N.C.N.C. sile. Mo gbọ wipe igbati o pe ọpọlọpọ awọn Obirin to nile lati ripe wọn da ẹgbẹ na sile kiakia ti nyọnu ni wọn yan Komiti kekere kan larin wọn lati wa aye bi idasilẹ ẹgbẹ ti Obirin na yio se ya kiakia.

Awọn to wa ni Kọmiti na je bi mejidinlogun. Ninu igbiyanju lati da ẹgbẹ na sile, awọn Komiti na se ipade pelu awọn igbimọ alase ti N. C. N. C. fun imọran ati ranlọwọ.

Lẹhin asepọ ipade bi meji tabi meta ni ẹgbẹ N.C.N.C. fi iwe sode lati pe awọn Obirin to nifẹ itẹsiwaju ati igbega Ilu Ijesa lati wa si ipade ti wọn yio fi idi ẹgbẹ na mu lẹ fun awọn Obirin.

Awọn Komiti ti awọn Obirin yan fun igbe kal ẹgbẹ ti wọn na sise pupọ. Gere ti iwe ipe jade fun wọn ni awọn na ti nka ofisirihi ẹgbẹ Obirin Ilesa lara. Gbogbo awọn ajaju Obirin ti wọn nfi ọrọ idasile ẹgbẹ wọn na lọ lo fi ifẹ gba lati pelu wọn.

Gbogbo awọn ẹgbẹ Alerọ ati Alẹte lọ gba lati fi ara mọ ẹgbẹ na Mo tile gbọ nibi pataki pe awọn ajaju Obirin bi B. T. Ogunseitan, Arabirin Ayọola ati awọn patakipataki miran lo gba lati faramọ ẹgbẹ na.

Awọn kan nse iye meji nipa wọn sugbọn emi gege bi enikan ko siyemeji nipa gbigba wọn lati faramọ ẹgbẹ N.C.N.C. nitoripe bi o tile je pe Ọkọ wọn wa ninu ẹgbẹ A. G. sibẹsibẹ awọn igbati ibawa ọkọ won ati awọn papa yatọ si ti ẹgbẹ A. G.

Mo gba pe lọjọkọjọ ko soro fun wọn lati yapọ fun ẹgbẹ na.

Lọna kọji, gbogbo awọn gbajumọ Obirin ti a le pe ni OBIRIN lo wa ninu ẹgbẹ NCNC Ogunlọgọ awọn iyawo gbajumọ lo si wa nibẹ pelu. Gbogbo Obirin to nise lapa bi awọn Olobi, aiata, Onisu, Onikoko ati bẹ lọ titi lo pelu wọn nse ẹgbẹ na. Nitorina, enikẹni le sọ pẹlu ami idaniloju pe gbogan na ko ti gba ese ni ọjọ idasilẹ ẹgbẹ na.

Mo gbọ wipe ẹgbẹ Ọlọpẹ na ti da ẹgbẹ Obirin sile. Emi ko gbọ, bẹni emi ko mọ, ṣugbọn bi Ọpọlọpọ enia ko ti se gbọ tabi mọ ọjọ tabi asiko ti wọn da sile. Obirin ti ko jeki emi le gba pe iro ni ni pe mọ ti awọn Obirin bi melo kan ti won nba wọn jo "Kuni mi laya" lọ jọ ti wọn wọ ajọ ofọ nku ijọba wọn

Mo tun gbọ wipe eran wipe awọn yio ya awọn Obirin lowo ni wọn fi ri iha ile na, mo si gbọ pe ojojumọ ni awọn diẹ na lọ nba wọn jo Mambo ati Kokoma nibi ti awọn Ọlọpẹ bati nse iwasu igboro ni ireti wipe awọn yio rọjọ na gba lọjọ iwaju.

Irohin nipa ipade na yio jade lọsẹ to nbọ lagbara Oluwa,



J. M. OBE
Oun je ọkan ninu awọn ajaju N CNC ni Ile Ijesa. Awọn Obirin ti da ẹka ti wọn sile ni ọjọ karun oṣu yi



EGBE IFELODUN TI ILESA
Ẹgbẹ yi je ọkan ninu awọn Ẹgbẹ Gbajumọ ati Bọkini ni Ile Ijesa. Bi wọn ti je gbajumọ ni awọn iyawo wọn gbajumọ pelu. Wọn ni Iyawo ọpọlọpọ wọn lo pelu Obirin to faramọ Ẹgbẹ NCNC ti awọn Obirin da sile ni ọjọ karun oṣu yi. Diẹ ninu awọn ọmọ Ifẹlodun yi wa ni Igbimọ alase ti NCNC.

## A NREṬI IṢẸ IRE AKUKỌ
(Bere lati ọjọ iwe 3)

Kini Ijọba Akopọ tise fun Ẹkun Ilẹ Yoruba? Balewa nse afikun ọna Reluwe oilẹ Hausa, beni Njoku ti fowọ si ki wọn mase Cement ati Glass ni ilẹ IBO lọbun. Kini ire tawa ri gba lọwọ Akuko?

Post Office Gbogbo ti Nbadiwe wa ni yi Asiko Arthur Prest ni wọn ti seto gbogbo rẹ patapata Komọlafe Ire wo le o mu wa ba lati Ekọ? Nitori Alaye yi ni Kanselọ ọsanganga n kan fi ipe mi ni were mo fesi ọrọ rẹ da. Ṣugbọn nigbati o je pe awọn lowa nidi eto ilewe mi ko ri ijade awọn iwe mi gbogbo. Bẹni asiwere ensi ti ma gbọn loju ara re pelẹ o Kanselọ Ojo, Adupẹ lọwọ Olọrun pe uni Igbimọ Ijọba Akukọ ni Ipinlẹ Ilesa loni. Ọlọla Fadahunsi ni Asoju Ijọba na. Ijọba Ipinlẹ ilu kọkan nini iṣẹ ilọsiwaju wa bẹ wa lọwọ rẹ. Akukọ ti fi ye gbogbo Ijẹṣa pe eto iṣejọba Ọpẹ ko dara rara. Ilọsiwaju ilu kosi lọwọ Ijọba Ekun. Ijọba Ibilẹ losi eto ituntun se Ijọba Ibilẹ lo ma nbu owo ori ni gbogbo ilẹ. Ọpọlọpọ tiri iṣẹ ilọsiwaju Ilesa abẹ Ijọba Ijọba Ọlọla Fadahunsi lowa loni, bẹ na ni ise omi pelu. Afojusọ ati ise iba die ati Ijọba Ekun.

Nisisiyi ni ọtitọ yio han, Ijesha ti gbe Ijọba Ibilẹ wọn le EGBẸ AKUKỌ lọwọ, Awọn sini olododo loju gbogbo ọmọ Obokun loni. Ọwọ Ijọba Ibilẹ sini ilọsiwaju ilu wa: Yio si dara ki Ọlọla Fadahunsi jẹki gbogbo araiye ma gbọ bi wọn base una gbogbo owo Ijọba Ijọba Ibilẹ ati owokowo ti wọn ba ya Ilesa lati Ibadan AKUKỌ loni Ijọba Ipinlẹ Ijesa nbọna ati pe nisisiyi gan lato le mọ boya ire kan wa ti Akuko yio se Ijesa! Nibikibi Akuko lakuko wọ! Akukọ ko se Yoruba lore ni!! Laipe yi ni wọn sọpe owo kan wa ti awọn rianwo ori ilu Oyinbo lati se iranlọwọ fun awọn ilu amọnaa won, owo na je ẹgberun pọun lọna ogorin £80,000,000. Inu gbogbo enia ilu amọna na lọdun kan pe awọn Oga wọn u niau rẹ fun fẹ se awọn lore.

Ninu owo yi Ẹgberun lọna Ẹgbẹrun lọna mẹtala le Ẹgberun lọna Ogorin pọun lọ kan gbogbo Akopọ Naijiria wọn fi owo yi rarse si Igbimọ Minisita Akopọ Igbati a ba nwọpe Akukọ kosi ire kan fun ilẹ Yoruba nitorikankan er'e nu yio ma ka Alebu Awọlọwọ lọwọ iwọ no'kawe mi so fun mi Edo enia wo lo wa ti kiio asiwere se kosi Rara! Igbati Igbimọ Minisita ma pin £13,000,000 wọn fun Ijọba Akopọ lo lowo lowọ ju gbogbo Ijọba yoku lọ "Se Ijọba Alakukọ ni"! ni £3,750,000 Ẹgberun lọna Ẹgberun lọna mẹta le Ẹgberun lọna aadọta leni Edegberin pọun Wọn fun Ijọba Ilẹ Hausa ni £4,750,000 Ẹgberun lọna ẹgberun mẹrin le ẹgberun lọna adọta leni ẹdẹgberin pọun Wọn fun Ijọba Ariwa ni £2,750,000 Ẹgberun ona Ẹgberun lọna mejeji Ẹgberun lọna adọta leni Ẹgbẹ un pọun Wọn fun Ijọba Kamerun ni £1,330,000 Ẹgberun lọna ẹgberun le ẹgberun lọna ọdu le ọgbọn pọun Wọn wa fun Ijọba Awa YORUBA ni Ẹgberun pọun lọna ẹbegbeta eyiti koto idamẹrin ti Ijọba ilẹ IBO!

Kini ẹṣẹ awa Yoruba lọdọ Ijọba Akukọ ti Akopọ? Wọn ni Ipinlẹ wa lowo julọ. Bẹni? Ipinlẹ ni ọran owo ori ti le. Ipinlẹ wa siri olọ ọkinju ninu gbogbo eto ilọsiwaju, ọe Ijọba. Ṣugbọn Ipinlẹ wa kolowo to Ijọba Akopọ, kini o wa fa iru iṣẹjẹ nla yi wa. Kosi nkan to fa ju pe Awa Yoruba lafi owo wa gbe olore wa suba tanwo odalẹ ọrẹ bi olododo enia bẹni kilẹ to pa tọdalẹ ọrẹ ọbun gantanganna sibẹjẹ. Ninu Gbogbo Ijọba Naijiria loni Ijọba ilẹ Yoruba toni owo nira ju fu iṣẹ omi kakiri gbogbo Ipinlẹ kọkan, fun iṣẹ nlanla ti ẹkọ ọfẹ fun gbogbo ọmọ Ilẹ Yoruba, fun eto ile Iwosan ati Ilera ati ọpọlọpọ iṣẹ nlanla miran.

Kini Akukọ se fun rarẹ gan o iru iṣẹ nla wọn yi ti Ijọba Ekun da wọle yi ọfẹ, owo pupọ Ṣugbọn Ijọba Akopọ fi agbara wọn yan Ipilẹ wa je bẹni ọpọọpọ owo Ijọba wa ni wọn nna fun atunse ilẹ IBO ati ilẹ Hausa fun irẹpọ Naijiria Irẹpọ yi lomn ti wọn fi gbe awọn iṣẹ Cement ati Glass lọ si ilẹ IBO kini anfani tari gba nipa idibo fun Ọlọla Olu. Kọmọlafẹ? Akuko kan ko mọ ọmọbibi inu rẹ ri. Gbogbo omi Naijiria ni wọn nfẹ rehin dada basi Ọlọla wa gbagbe pe wọn le fẹ omi Ọni na dada ko gba ẹko ẹlẹfin. Nipa eyi Titi ẹsa Eti Ọni yo di titunse lati ọwọ Ijọba Akukọ! Ijọba Ibilẹ satida rgaala yona yi.

Lọsiwaju ilẹ Ijẹṣa dọwọ Ẹgbẹ Akukọ sibẹ na Asi meti Ire ti Akukọ yio se fun Ilẹ Ijẹṣa nise ti Ijọba Ibiẹ wa wa lọwọ wọn lọni!!



KANSẸLỌ M. I. EKUNDARE

On jẹ okan ninu awọn aṣaju NCNC. On na pẹlu awọn ti awọn Komiti Obirin ba se ipade pọ lati gba imọran ati iranlọwọ fun idasilẹ Ẹgbẹ tiwọn.



GBỌNGAN OBOKUNGBUSI

Nibẹ ni wọn t'se ipade idasilẹ Ẹgbẹ Obirin ti NCNC ni ọjọ karun oṣu yi. Gẹgẹbi irohin imurasilẹ ti a ngbọ, o daju pe gbọngan na yio kun fun awọn obirin to fẹ ṣẹ ara mọ ẹgbẹ na

## AKUKỌ KU SINU AGO KIṢE ẸBI ỌPẸ (Apa Kini)

(Lati Ọwọ Kanṣẹlọ G. Ade. Aromọlaran Amuye)

Ẹnyin ọmọ Obokun nile ati ni idalẹ mo fẹ ki ẹ fi okan si ọrọ ti mo fẹ bẹrẹ si lati ma ba nyin sọ lori ọrọ ikusago Akukọ yi, ki ẹ si fi oju inu wo iwa Akukọ ti igba arọ, eyi ti ọmọ ẹyẹ (Ọgbẹni Aiyekotọ) fi ẹnu kan niwọn nkan bi ọjọ melo kan sẹhin, pẹlu awọn Akukọ ti ode oni yi.

O jẹ ohun ti o ya mi lẹnu wipe lẹhin ti Adiẹ (Akukọ) ti ku sinu ago ile rẹ, ni ilẹ Ijeṣa, ẹnikan tun nwa ọna lati ji dide, nipa wiwa irọ tuntun eyiti yio tun mu awọn ọmọ Obokun lori kankan pa ki nwọn bale, baji oku Adiẹ: Mo fẹ ki iru enia bẹ, iba jẹ wipe awọn Akukọ gbe owo fun ni, iba jẹ iṣe ni awọn Akukọ gba Oluwa oluwa rẹ sin ni, ki o lọ ki ọwọ ọmọ rẹ bọ aṣọ niloripe igbayi ko jọ ti ẹrẹkan mọ ko si ẹniti o nlo oku Adiẹ ni ile Obokun:

Ọrọ Akukọ di igba meji ni Ile Obokun.

Eyi ni o ṣe igba keji ti Akukọ yi o ṣe idina ire fun ilẹ Obokun, ẹnyin ti ko ronu ọmọ adiẹ ti ẹ jẹ tan ti ẹ mu tan ti ẹ nfi Ọpẹ ṣe ẹlẹya bẹni ẹ si mọ wipe inu rẹ ni ẹ nsun, bi ẹ gbe ju ọdun mẹta laiye ẹ ko ni ile miran ju ago lọ.

Ẹnyin ọmọ Obokun emi ro wipe iru iwa aimore bayi lo mu ki ẹnikan ninu awon ọmọ Adiẹ sọ wipe ko si ore ti Ọlọla Awolọwọ ṣe fun on tabi ẹnyin ọmọ Obokun, mo si fẹ ki iru adiẹ bẹ ti o ba ma sọrọ ki o sọ si awọn ẹiyẹkẹyẹ ẹgbẹ rẹ ki o ma fi ẹnu kan ti awa ọmọ Obokun nitoripe awa yatọ si Adiẹ ẹgbẹ ẹja ni ẹja si nwẹ tọ.

Ti' ori kan ba sunwọn yio ran 'gba ori, mo fẹ ki Ọgbẹni Adiẹ mọ dajudaju wipe ti ori kan ba sunwọn nṣe ni o nran igba ori. Ori awọn adiẹ (Akukọ) nikan lo fẹrẹ sunwọn ju fun eto ile iwe ọfẹ ti Ọlọla Awolọwọ gbe kalẹ yi iba jẹ wipe ko si ile iwe ọfẹ, ni ọpọlọpọ Akukọ ni awọn obi miran iba ti ko ta fun a ti san owo ile iwe wọn, bẹ si ni enia ko le ra Akukọ sin ibi pipajẹ lo mọ.

Irufẹ eleyi ni awọn onilu ri ti nwọn fi ma nfi ilu palowe wipe: "Ọbafẹmi ọmọ Awolọwọ iwọ lari ba wi, iwọ ti o gbe 'da lọwọ ti o ko fi pa Akukọ iwọ la ri bawi Ti o sọ ile iwe di ọfẹ ti o fi nda ẹmi akukọ si, ti o sọ Ile-iwosan di ọfẹ ti o fi nda bo bo adiẹ iwọ lari bawi"

Ṣugbọn Awolọwọ ko jẹbi fun iru iwa anu ba yi, awọn ọmọ adiẹ ni ko ni ore lara iwa aimore ni ko jẹ ki aṣọ nwọn pe meji on lo si mu ki gbogbo ẹiyẹ ma fo ti nwọn ko fi ni iyẹ niti wọn.

Ẹ mu tọrọ nyin dani di ọsẹ ti o mbọ, nigbati ngo ma ba ọrọ mi bọ. O di 'gba diẹ o.

G. A. Aromọlaran.



ỌGBẸNI E. A. EKUNṢEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ ti Ẹgbẹ NCNC ni Ilẹ Ijẹṣa. Awọn Obirin Ilesa ti da Ẹgbẹ NCNC ti Obirin sile ni ọjọ karun oṣu yi. Wọn ni nibin idasilẹ na yio ijade lọṣẹ to nbọ.



APETU TI IPETU (AGUNSIADE KE I)

Ni idahun si Ọrọ Akọwe Afẹnifẹre, ẹnikan so ninu iwe ọsẹ yi pe awọn Oloye to fi ara mọ́gbẹ ijẹlu ni akamọ wọn ko gba ni Alaga.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu

## "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan; |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## SAMUEL OGUNDIRAN NI LORIỌMỌ WA
Lati Ọwọ Ara Iṣida)

Jọwọ Olotu Irawọ Obokun Inu mi yio dun pupọ ti o be le gba mi laye lati fesi si ọrọ ro kan ti awọn kan ti wọn pe ara wọn ni Ọmọde ati Agba Iṣida pa ninu Irawọ Obokun ti ọjọ 30-5-55 Awa Ojulowo ọmọde Iṣida ati agba Iṣida lo nfi esi wipe awa ko yọ Samuel Ogundiran ni Loriọmọ Iṣida wa o

A si tun nsọ siwaju si wipe ni ọjọ ti a ma yan Samuel Ogundiya ni Loriọmọ Iṣida Ibo ni a fi yan ko si bẹ awa ara Iṣida lati fi on ṣe Loriọmọ ṣugbọn Ibo la fi yan o ko si ṣe awa ara Iṣida o Nitorina awa Asan-owo-ori Iṣida ati Agba Iṣida ko kọ Samuel Ogundiran ni Oloriọmọ wa o.

## AWỌN ỌMỌDE NGBA BỌLU LOJU ỌNA MOTỌ
(Lati Ọwọ Gabriel Adegbite H 45 Ilọrọ Ileṣa)

Jọwọ Olotu gba mi laye diẹ la ti e alaye diẹ lori awọn ọmọ ti fibi iṣere nlẹ to jẹ pe oju titi Ijọba ni Bọlu yẹ le ti ma gba ki ẹ ehin ninu ọrọ mi Olọrun ko gba wa lọwọ awọn ọmọkunrin to jẹ pe wọn ko gbọ ọrọ si awọn obi wọn lẹnu

Igba pupọ ni motọ wa nse wọn ese to si jẹ pe awọn ọmọ bubu-u yi ko bikita ikan kan sẹlẹ sẹlẹ bẹni mo ro nu si pe moto ni Ijọba se titi fun ki se bọlu ọlọ ni Ijọba se ilu ibi iṣere Bọlu si emi si ronu si pe ko yẹ pe ki bọlu ma di motọ lọwọ ni ọna ti wọn ti ri mo ro ronu si pe ki moto la lọ ko la iru awọn ọmọ oni-bọlu oju titi wọn yi iṣẹgbogbo rẹ yio di ti oni motọ idanu rẹ yio jẹ ti awọn obi ọmọ bẹ tori na mo bẹ awọn Ọlọla wa ni ilẹ Ijeṣa mo si tun bẹ Baba wa Ajimọkọ Keji awọn Ijoye pẹlu, mo tun bẹ obi awọn ọmọ na pe ki wọn ba fi ọrọ na si ofi ki awọn ọmọ ma se ma gba Bọlu

## AWỌN ONITẸTẸ.
(Bọrẹ ni oju iwe 1)

wọn sa lọ si igbo.

Ogbeni kan pẹlu, o ra koko ka lẹ lati Irogun o wa ra si Ikorun Idominasi. O ku £7 si lọwọ. Wọn bẹ ki o wa ta tẹlẹ ona on ko la. Nigbati ko si ero kankan ni Ikorita na wọn gba gbogbo owo ti o ku na Nigbati wọn gba tan, wọn sa ọ si igbo.

Onisowo kan ti o nti ọna jinjin bọ, o fẹ lọ se igbeyawo owo ti oma lọwọ jẹ £50. Awọn onitẹtẹ gba £30 nibẹ wọn pa Okunrin yi lẹkun. Owo igbeyawo rẹ koto mọ. O wa pada si ilu rẹ ni Zaria.

Mo dupẹ pupọ lọwọ yin ẹjọwọ ki ẹ ba mi gba ọrọ na yẹwo. Ọpọlọpọ ero ti o fẹ ma wọko ni Ikorita yi, wọn ko duro nibẹ nitori awọn enia ibi yi. Eo tun ma gbuso mi si ehin o. Mo ki Olotu Ọkọ Ọba ko ni ṣayin lẹse. Ọlọrun yio da ọmọ si o. Amin.



ARABIRIN OGUNSEITAN

On na je okan ninu aṣaju awọn Obirin Ileṣa. Ogunlogo awọn Obirin na lo faramọ lati jẹ ọmọ Ẹgbẹ NCNC ẹka ti Obirin. Wọn ni Arabirin wa yi yio pẹlu wọn laipẹ.



KANSẸLỌ J. A. AKINYEMI

On ni Alaga fun Igbimọ Ijọba akamọ ti Ifẹwara (Ifẹwara Local Council) ni idahun si ọrọ Akọwe Afẹnifẹre Kanselọ S. Akindele Ojo nbere pe kinise ti wọn ko fi Ọba Ifẹwara ṣe Alaga ti ọrọ re ba jẹ otitọ.

## ỌRỌ LORI IBUSỌ MỌTO
(Lati Ọwọ Gabriel Awe Omi Adio)

Si Olotu Irawọ Obokun, jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ olooyinmọmọ lati se alaye diẹ lori ibusọ motọ Ileṣa. Mo ki ẹnyin oselu wa lọmọde lagba mo ki Ọwa Ajimọkọ II ati awọn Ijoye rẹ pelu, pe ẹ ku atunse ilu. Ẹ ku ọgbọn inu Ẹ ku ṣuru. Ẹ jọwọ ọrọ lori ibusọ moto ni mo fẹ sọ. Ẹ jọwọ bi ẹ ba ri pe ẹ mara tan, lati se ibusọ moto. Ẹ ma jẹki enikan ki o mu irewẹsi ba yin nipa rẹ.

Kini idi irẹwẹsi; nigbati enikan ba ran yin l'eti ohun ti ẹ ti seto silẹ, ti enikan tun nse alatako re Tani alatako? Alatako ni Ọgbẹni S. A. Obọdo B 153 Okeṣa Nigbati Ọgbẹni E F Fadahunsi J. 125 Ilẹmọ Street Ileṣa. Ran awọn oṣelu wa leti fun eto ti wọn ti ronu si ti wọn si ripe o dara, ti Ọwa Ijoye fi ọwọ si; ti Ajẹlẹ kekere ati Ajẹlẹ Agba fi ọwọ si ti awọn Ijọba si na ọpọlọpọ owo sibẹ

Ọgbẹni S A Ọbọdo so pe ko dara ni t'ohun, Mo rope Ọgbẹni yi jẹ okan ninu awọn alawaui mẹta ti ... Ọgbẹni kanna yi fi ye wa pe, ohun gbọ pe Ijọba NCNC mura tan lati se ibusọ motọ na ki o dara bi ti Ibadan, Abẹokuta, Eko, Ilẹ Oṣogbo ati orisirisi ilu miran. Ọgbẹni kan na yi tun nsọ ninu ọrọ re pe, bi a ba da ọja titun ti ibusọ moto ko ba si nitosi re, tabi arin ọja, ohun kọpẹ anaru ni on ri iru owo bẹ ri. Mo rope Ọgbẹni yi ko tiẹ ona si gbogbo ọrọ yi ko to sọ. Tabi o ti lẹ fẹ jẹ alatako lasan ni? Idi ti mo fi sọ be ni wipe gbogbo ilu ti Ọgbẹni yi daruko ke si eyiti ibusọ moto wa larin ọja wọn Awa ko fẹ fi ta ọja se, bikose ọpọlọpọ awọn ọna ti o fi oti sọ ibiti a wi yi

Ẹ jọwọ enyin Ijọba, Ẹ ma fi eti si ti Alatako, Ẹ se ohun ti ẹ ti ronu si ti ẹ si tiri pe o dara. Ti ẹ si ti fi ọwọ si. Obokun a gbe yin o. Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi Ọkọ ọba ko ni sa yin lẹse


# WANTED URGENTLY

**Four Journey-men and Four Apprentices.**


# AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B110 & B149 Okesha Street, Ilesha 6 - 6 - 55